# IṢẸ - IYANU KIN-IN-NI TI JESU ṢE ATI WÍWẸ TẸMPILI MỌ́

### Johannu 2:1-25

### ẸKỌ 28 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Ile adura fun gbogbo orilẹ-ède li a o ma pè ile mi” (Marku 11:17).**

**Ju Eniyan Lọ**

Ni gẹrẹ ti iṣẹ-iranṣẹ Jesu Oluwa wa ni ode gbangba bẹrẹ ni O fi agbara nla Rẹ̀ ti o ju ti ẹda lọ han fun awọn eniyan. O fi han pe Oun ju eniyan kan ṣa ti o wa fi igbesi aye rẹ̀ ṣe apẹẹrẹ fun awa ẹlẹgbẹ rẹ lọ. Gẹgẹ bi a ti kọ ninu ẹkọ wa iṣaaju, Jesu dọgba pẹlu Ọlọrun ninu dida aye. Ohun ti o kàn ni lati ṣe ni pe ki O sọrọ, a si da aye. Ni ifiwera, o jẹ ohun kinkinni fun Ọmọ Ọlọrun lati sọ omi di ọti waini, ṣugbọn o gba agbara ti Ọlọrun kan naa lati ṣe e.

**Sọ Fun Jesu**

A ti pe Jesu si ibi iyawo, O si lọ pẹlu iya Rẹ̀ ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. Gẹgẹ bi aṣa, wọn jẹ ase lẹyin igbeyawo. Lẹyin igba diẹ, waini bẹrẹ si i tan; nigba ti Maria si gbọ eyi, o sọ fun Jesu pe, “Nwọn kò ni waini.” Nigba ti a ba n fẹ nnkan kan, ohun ti o dara ni lati sọ fun Jesu nipa rẹ. Inu Jesu ki i dun nigba ti awọn ọmọ Rẹ̀ ba n ṣe aroye nitori pe wọn kò ni ohun gbogbo ti wọn n fẹ. O wi pe Oun mọ ohun ti a ṣe alai ni, bi a ba si beere pẹlu igbagbọ́ Oun yoo fi i fun wa. Nitori naa bi a ba wa ninu aini tabi wahala, a gbọdọ sọ ọ fun jesu; bi o ba si ṣe ohun ti o dara ju lọ fun wa lati ni ohun ti a n beere, Jesu yoo fi i fun wa.

A ko mọ bi Maria ati Jesu ti ba ara wọn sọrọ to (ṣaaju akoko yi) nipa wi pe Jesu yatọ si awọn eniyan miiran, ṣugbọn Ẹmi Mimọ ti sọ fun un ki a to bi Jesu pe a o maa pè E ni Ọmọ Ọga-Ogo ju lọ, pe Oun ni yoo gba awọn eniyan Rẹ̀ la kuro ninu ẹṣẹ wọn, ati pe Ijọba Rẹ̀ ki yoo nipẹkun. O ti “pa gbogbo nkan wọnyi mọ́ o n rò wọn ninu ọkàn rẹ” (Luku 2:19). Nisinsinyi o ni idani loju pe Jesu ni agbara lati ṣe ohun gbogbo, O si le ran olori ase naa lọwọ ni akoko idaamu rẹ.

**Igbọran Pipe**

Maria sọ fun awọn iranṣẹ lati ṣe ohunkohun ti Jesu ba sọ fun wọn lati ṣe. Eyi ni aṣiri gbigba ibukun lati ọdọ Oluwa. Jesu fẹ ki a wa sọdọ Oun ni ọna naa ti O ti la silẹ ninu Ọrọ Rẹ̀. Ko si ọna miiran lati ri igbala ju ati wa sọdọ Jesu ni ironupiwada awọn iṣe buburu wa, ki a kọ wọn silẹ; ki a si gbà A gbọ́, gẹgẹ bi Bibeli ti wi. Nigba ti awọn onigbagbọ́ ba n fẹ ohun kan lọwọ Ọlọrun, wọn gbọdọ wa pẹlu ifi-ara-ẹni-rubọ, ki wọn si fẹ lati ṣe ohun ti O fẹ ki wọn ṣe. Nigba naa ni a o fun wọn lere.

Nigba ti Jesu ba sọ fun wa lati ṣe nnkan kan, O ni ireti pe a o ṣe e. Aigbọran n mu wahala wá gẹgẹ bi o ti ṣe fun Jona, nigba ti Ọlọrun sọ fun un lati lọ waasu fun ilu buburu ti a n pe ni Ninefe, iṣẹ ti a ran an ni pe a o pa a run. Oun kò fẹ lọ, nitori naa o wọ ọkọ ti o n lọ si ọna miiran, o gbiyanju lati sa lọ kuro lọdọ Ọlọrun. Ṣugbọn a ko le sa kuro niwaju Ọlọrun.

Iji nla dide, afẹfẹ si n ti ọkọ naa sihin sọhun titi awọn awakọ naa fi ro pe awọn yoo rì sinu omi. Jona ri i pe ẹṣẹ oun ti wa oun rí, nitori naa o sọ fun awọn eniyan naa lati ju oun sinu omi, iji yoo si duro. Ọlọrun ti pese ẹja nla kan silẹ lati gbe Jona mi ki o ma baa tilẹ le rì rara. Ọlọrun ṣi lè rí i sibẹ ni isalẹ okun, ninu ẹja nla, O si beere lọwọ rẹ bi o ba n fẹ lati lọ nisinsinyi. Lẹyin ọsan mẹta ati oru mẹta, Jonah n fẹ lati gbọran si Ọlọrun lẹnu, ki o si lọ waasu fun awọn ara ilu Ninefe.

Ọlọrun le má fi ọwọ lile bẹẹ ba wa lo: ṣugbọn ohun ti o buru gba a ni lati ṣe aigbọran si Ọlọrun, a ko si le maa reti ibukun Rẹ̀ ti a ba ṣe bẹẹ.

**Imura Silẹ Ṣaaju Ibukun**

Iba ti rọrun fun Jesu lati sọ wi pe, “Ki waini ki o wà,” waini iba si wà. Ṣugbọn nigba miiran, Ọlọrun n fẹ ki a ṣe nnkan kan ṣaaju. Igbakuugba ni Jesu maa n wo awọn alaisan san nipa sisọ pe, “Ki iwọ ki o mọ́” tabi “Dide, gbe akete rẹ, ki o si mã rin;” ṣugbọn ni igba kan ti O wo afọju kan sàn O kọ ṣe amọ̀, O si fi i si oju rẹ, lẹyin naa O wi fun un pe ki o lọ wẹ ninu adagun Siloamu. Nigba ti afọju yii gbọran, oju rẹ la, o si le riran.

Nigba ti a ba tọ Jesu wa fun isọdimimọ tabi lati gba agbara Ẹmi Mimọ́, Ọlọrun n fẹ ki a ṣe ifi-ara-ẹni-rubọ ti o jinlẹ. Nigba miiran awọn ifi-ara-ẹni-rubọ wọnyi jẹ fifi ohun pupọ du ara wa; a ni ohun kan lati ṣe ki Oluwa to le mu ifẹ wa ṣẹ. Nigba ti a ba ṣe ipa ti wa, Ọlọrun yoo ṣe ti Rẹ̀.

**Ere Igbọran**

Awọn iranṣẹ naa pọn omi kun inu awọn ikoko gẹgẹ bi Jesu ti sọ fun wọn lati ṣe; o le ro bi yoo ti ya wọn lẹnu to nigba ti wọn bu waini jade – waini ti o dara, ju eyi ti wọn ti n bu lọ lati ibẹrẹ.

Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe olori ase naa ko mọ̀ ibi ti waini daradara naa ti wa, ṣugbọn awọn iranṣẹ mọ. O da wa loju pe wọn sọ fun gbogbo eniyan ti o wa nibẹ, ṣugbọn Iwe Mimọ sọ wi pe awọn ọmọ-ẹyin gbagbọ. A mọ pe ni igba pupọ lẹyin eyi nigba ti Jesu ṣe iṣẹ-iyanu, awọn ẹlẹṣẹ kò bu ọla fun Un.

A ri iru iwa bayii lonii pẹlu. Ẹni kan le ṣe aisan pupọ tabi ki o fara pa pupọ, alaigbagbọ kan le wi pe "Bi ọkunrin yii bá sàn, emi yoo gbagbọ́ pe Ọlọrun ni o ṣe e;" ṣugbọn lẹyin ti a ba ti ṣe iṣẹ-iyanu yii; oun yoo wi pe, "Ko le pupọ to bi a ti lero." Awọn eniyan ki i fẹ gba Jesu gbọ́ lonii, wọn maa n gbiyanju lati gbé oju fo iṣẹ-iyanu dá. Ọlọrun maa n fi ibukun pupọ ti o ya ni lẹnu fun awọn ti wọn ba gba A gbọ, ti wọn si n bu ọla fun Un.

Jesu naa ti a n sin ṣe iṣẹ-iyanu ti a ko le ka tan, nigba ti O wa ni aye. Johannu wi pe, "Bi a ba kọwe wọn li ọkọkan, mo ro pe aiye pãpã ko le gba iwe na ti a ba kọ." Ninu Heberu, a ka wi pe "Jesu Kristi ọkan na li ana, ati li oni, ati titi lai." Awọn iṣẹ-iyanu ti Jesu ṣe nigba naa ni O si n ṣe lonii pẹlu laaarin awọn ti o gba A gbọ. Iṣẹ-iyanu ti o tobi wo ni o wà ju pe ki a gba ẹlẹṣẹ là kuro ninu ọgbun ẹṣẹ, ki o maa gbe igbesi-aye mimọ́, ki o si maa rin deedee lati ọjọ naa lọ? Kò ṣoro fun onigbagbọ tootọ lati gbagbọ pe Jesu sọ omi di waini.

### A Sọ Ile Ọlọrun di Aimọ́

Ẹẹkan ni a maa n ṣe Ajọ Irekọja lọdun ni Jerusalẹmu, akoko Ajọ naa si ti de. Ajọ Irekọja yii ni lati jẹ ipejọpọ ọ̀wọ̀, nigba ti awọn Ju ni lati ronu idasilẹ iyanu ti Ọlọrun ti ṣe ni mimu awọn baba nla wọn jade kuro loko ẹru Egipti ni nnkan bi ẹgbaa ọdun sẹyin. Ṣugbọn awọn Ju ti sọ ẹmi ọ̀wọ̀ ti ajọ yii nù ni ọjọ pipẹ sẹyin, wọn si n lo anfaani ajọ yii lati wa owo nipa iṣowo.

Apa kan ninu eto ajọ yii ni fifi ọdọ-aguan "ti kò labuku ti kò si ni abawọn" ṣe irubọ. Ko rọrun nigbakuugba fun ẹbi kọọkan lati le ri iru agutan bayii ni aarin ilu nla, nitori naa awọn alufaa maa n tọju awọn agutan si arọwọto ni agbala ode ti Tẹmpili: pẹlu awọn ẹran miiran ti a n lo fun irubọ oriṣiriṣi ni oniruuru igba ni aarin ọdun. Awọn onitan sọ fun wa pe nigbakuugba ni awọn alufaa ti kò ni itọni ẹri-ọkan mọ maa n kọ̀ ẹran ti olusin ba mu wa. Wọn a ṣe bi ẹni pe ẹran naa ni abawọn, wọn a si paarọ rẹ, pẹlu owo ti ẹni naa yoo fi kun un, pẹlu eyi ti wọn sọ wi pe kò labuku. Lẹyin naa wọn a si ta ẹran ti wọn ni kò dara yii fun ẹni ti o ba tun wa fun irubọ lẹyin eyi. Wọn n ṣe gbogbo eyi lati fi ko owo jọ.

Jesu ni "ọlọkan-tutu ati onirẹlẹ ara Nasarẹti." Oun kò si wa okiki ati ọla fun ara Rẹ̀. "Ẹni, nigbati a kẹgan rẹ ti ko pada kẹgan." Ṣugbọn nigba ti O ri i pe a ko bu ọla fun ile Ọlọrun, ti O si ri iwa abuku awọn oniṣowo wọnyi, O dide ni ibinu, O le gbogbo wọn jade, pẹlu awọn ẹran wọn, O si yí tabili awọn onipaṣipaarọ owo danu. O kigbe wi pe "Ẹ máṣe sọ ile Baba mi di ile ọjà tità." Ninu Matteu, a kọ ọ pe, "Ile adura li a ó ma pè ile mi; ṣugbọn ẹnyin sọ ọ di ihò ọlọṣà." Eyi fi hàn wa bi a ti gbọdọ ṣọra to lati lo ile Ọlọrun ni mimọ́, a kò si gbọdọ ṣe ohunkohun ti yoo tabuku si i.

### Idajọ Otitọ Tabi Aanu

A le ti maa ro pe pẹlu ọpọlọpọ eniyan bẹẹ ninu Tẹmpili, wọn iba ti sowọpọ lati kọju ija si Jesu; ṣugbọn nigba ti Idajọ Ọlọrun ba sọkalẹ, ko si ohun ti eniyan le ṣe ti o le da a duro. Ni ọjọ ikẹyin, awọn ẹlẹṣẹ yoo kigbe pe awọn apata ati awọn oke lati wó lu wọn lati pa wọn mọ kuro ninu ibinu Ọlọrun, ṣugbọn ni ọjọ naa ko si ohun ti yoo da ibinu gbigbona Rẹ̀ duro. Nisinsinyi, O kun fun aanu, O si n dariji olukuluku ẹni ti o ba ke pe E; ṣugbọn nigba ti ọjọ aanu Rẹ̀ ba kọja, kò si ohun ti yoo da idajọ ododo Rẹ̀ lori awọn eniyan buburu duro.

## AWỌN IBEERE

1. Njẹ o ro pe ìyá Jesu n reti pe ki O ṣe iṣẹ-iyanu kan?
2. Njẹ awọn iranṣẹ naa mọ ẹni ti o sọ omi di waini?
3. Ki ni olori ase naa sọ nipa waini yii?
4. Njẹ Kristi ti ṣe awọn iṣẹ-iyanu kankan ṣaaju igba yii?
5. Bawo ni a ṣe gbọdọ huwa ninu ile Ọlọrun?